# ADAJỌ SỌ ADELABU SI EWỌN OSU MEJI

**Ikede**

Ase ikede yi fun gbogbo Enyin Okawe wa ati asoju wa wipe, enikeni ti owo ba seku si owo re ki o tete fi ranse nitori gbogbo ohun elo ti a fi nsiwe irohin lo ti gbe owo leri.

Enikeni ti ko ba fi tire ranse ao da iwe re duro ao si sa agbara lati gba owo wa ni owo re. Olotu


ELETI OFE

A-NJU-WỌN KO SE WI L'EJỌ


**Ohun Iyanu Kiitan**

Odidi apa-otun enia kan ni nwon ri ninu ipho nitosi Otto l'ona Ibute-Metta.

Ako mo eniti o ni apa na o.


VOL VII No 430 LAGOS (SATURDAY) OJO ABAMETA AUG 27 1955, IYE OWO ELETI OFE KOBO MEJI (2d)


## Ejo Iku Njemanze Yio Bere L'osu T'ombo



Ejo iku Akorin Olohunyo ti oruko re nje Njemanze ara ilu Ibo, ti nwon ji ba oku re ti nwon ge lekiri-lekiri da sile l'oju irin oko-ile (Railway line) l'owuro ojo kejo osu April nitosi iyana si Surulere l'oke Ebutemeta, yio bere ni Kotu Ganran n i n u osu t o m b o y i.

Enyin okawe wa yio ranti wipe Isreal Njemanze (ti adape oruko r e n j e Nwaoba) yi ni eniti nwon sa pa ti nwon si ko da si oju irin o k o Reluwe gegebi enipe oko Reluwe l'opa Nigbati awon olopa oba (Otelemuye bere si se iwadi nipa re, enia merindinlogun ni nwon fi sun e s u n apa-nia sugbon Kotu kekere da awon enia mejo sile fun aiko ni eri to lati ba won rojo.

Awon enia mejo yoku ni yio duro ro'jo l o r i iku odomodekunrin osere ol hun'yo ti nwon pa nipa oro yi, Dada Owolabi pelu awon enia meje ni yio duro sonson niwaju ate idajo.

## Adajo So Adelabu Si Ewon Osu Meji Pelu Ise Aṣekara



Ni ojo kedogbon osu yi ni Adajo Kotu Onireke ni ilu Ibadan da ejo Ogbeni Adegoke Adelabu ati Lasisi Ade Bello ti se isongbe Adelabu bi Alaga ile Igbimo Ibile ti ilu Ibadan.

Niba soki: Adajo so ninu idajo re wipe on gba pe otito ni awon odaran na se si esun ti a fi won sun ti wipe gbogbo awawi ti nwon se lati fi ja ajabo ko moyan lori, Nitorina won jebi esun ti a fi won sun. ki Ogbeni Adegoke Adelabu lo si ewon osu meji ki Lasisi Ade Bello lo si ewon osu mefa pelu ise asekara.

Abo re o, enyin o k a w e wa, o f i n k o mo Oba, beni ko mo eni-owo, ayafi mo'won arare.

## Gomina Agba Be Ile Igbimo Nla Wo

Ni ojo Monday ti ise ojo kejilelogun ni Gomina Agba fun apapo Ijoba Naijiria (Governor General f o r t h e Federation of Nigeria) be ile Igbimo apapo nla wo, (House of Representative) o si ba awon Ọlọla Olugbimo soro niba Soki.



ỌLỌLA GOMINA AGBA

Gomina agba so ninu oro re wipe, gegebi iwe eto iselu ti gba on laye lati wa sinu ile Igbimo yi, ki on si ba yin soro, ni on ro si eto loni, ki se wipe on ko ni oro pataki lati ba yin so sugbon niwon igbati a ti yan on gegebi Gomina Agba gbogbo Ijoba Naijiria, on ni ero wipe enyin na yio gba pe eto ni fun on lati wa ba yin pade, ki on si fi ara on han yin.

Gomina agba gba won ni iyanju o si fun won ni imoran lori ayipo won, gegebi ise ti nwon ni lati ma a se fun ire ati ilosiwaju ilu Naijiria, o si fihan wipe ko si Ijoba ajumosepo ti ko ni ni ijo alatako, sugbon bi Ijo ti ijoba ati ti a'atako ba ni lakayei ba ara won lo, ire ati alafia ilu yio ma te siwaju ni.

Gomina Agba so wipe eyiti o fe tako ero ti on ni ti ereke-ebu ti awon Olugbimo ma nsaba se, ninu ile Igbimo, ni arin ita gbangba ati ninu awon Iwe Irohin, o fi han wipe irufe iwa bawonni ko le mu ilosiwaju ba wa gegebi ati edu lati di ominira lowolowo yi.

Nitorina ki a dekun iru iwa be.

Oro Gomina Agba lati ori aga-Ola ninu ile Igbimo apapo nla je oro iwuri ati isinileti fun awon Olugbimo wa, ti o ba ni okan ati sise rere fun alafia ilu wa Nigeria.

## Oloye S. L. Edu



Oloye S. L. Edu Asoju ilu Epe ninu igbimo Ijoba Iwo Orun.

Fun ilosiwaju ilu Epe, Oloye Edu ni ki gbogbo omo Epe je okan soso, On ni alakoso Egbe Faramora,

Oloye S. L. Edu nsise to wuni lori fun idagbasoke ilu Epe ninu Ajo Igbimo.

## Dokita Fihan Wipe

### Ose Palmolive Le Jeki Oju Re Dara
LARIN OJO MERINLA



Arabinmi Jolo o tun Jide Nisisiyi ti mo tele ilana

Palmolive

Iba ohun ti iwo yio se niyi:- 1. Fi ose Palmolive we oju 2. Fi hiho re pa oju fun iseju kan. 3. Fi aso uu kuro se be nigba meta lojumo fun ojo merinla




EPO ILE AFRIKA

NI A FI SE OSE YI

COLGATE PALMOLIVE SOAP

## Isomo L'oruko

IKERE - EKITI. A se isomo loruko fun omo Ogbeni John Adekunle ati iyawo re nilu yi, ninu ile won ni Igele l'ose tokoja.

A so omo na ni Sunday Adekunle l'oju opolopo awon enia pataki - pataki.

Awon sara i enia to peju pese sibi isomo loruko na ni awon Ogbeni Samuel Ashamo, James Jonsbe, Zeccheous Ola ju, O'orunfemi, Jacob Darum la, Olawunmi Osho, Ezekiel Aro, Micheal Adeniyi, Akinola Olorunsomo ati Joshua A monium, pelu awon enia ti a ko le daruko tan.

Ki Olorun da Sunday si o.

## Olopa Segun Awon Egbe Olosa.

EKO - Irohin gbojikan kakiri ilu Eko wa yi wipe awon egbe olosa npeleke si latin ilu ati wipe ise jamba ti nwon nse fun awon ti awon olosa na ba wole won kokere.

Irohin ti a gbo ni wipe awon olosa wonyi lo fo Sabe okunrin kan ni Tapa Street, nwon si fi igo fo onisabu na lori, odid ijo maru ni nwon fi teju re n e Iwosan (General Hospital.)

Ng au awon jagun na de'bc awon en a ke pe awon olopa, iesekese, Moto awon Olopa m je ti de, owo si te die nu awon egbe ole na, nwon si gba ninu eru ti won ...

Owo awon olopa ti te enia mefa ninu awon ole na, gegebi a ti gbo, a si gbo wipe awon enia meta laku ki owo olopa ba, nwon si ni ero pe awon yen ti sa jade nilu.

A gbo wipe ijo meji ni awon egbe olosa to nda ilu Eko l'amu yi, awon olopa si nse itose ijo kan yoku nisisiyi.

A ni lati dupe gidigidi fun awon olopa oba fun wahala t' san t'oru won lori awon enia majeki t'anja suewon wonyi, lati le fi aya ilu Eko bale,

---

**Always Read And Advertise In Eleti-Ofe**

ELETI OFE
A-NIJ-WON KO SE WI L'EJO
EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLES & TELEGRAMS
28 Kosoko Street Lagos "ELETI-OFE LAGOS"
P. O. Box 467 Phone 23370
VOL. VII NO. 450 LAGOS SATURDAY AUG. 27 1955.

# Oro Gomina Agba Ninu Ile Igbimo Nla

Gegebi a ti se irohin nipa oro iwuri ati isinileti ti Qlola Gomina agba so lati ori-aga-Qla ninu Ile Igbimo apapo nla (House of Representative) l'ojo Monday ose yi, ni o mu wa fe gba awon ololo Olugbimo wa ni amoran leri gbolohun kan to wa ninu oro Qlola Gomina agba na.

Gomina agba so ninu oro re wipe, yio je ohun ti o dara bi awon olola Olugbimo ba le dekun oro bi ereke ebu tabi ki a ma g'asa funra eni ninu ile igbimo nla to je pataki fun ise ilu Naijiria, ati pe bi gbogbo nkan ba ti nlo si ninu ile Igbimo mbe lowo eniti o ba je alaga fun ile Igbimo na.

Nitorina ni a se ro si eto lati ran awon ololo Olugbimo wa leti wipe yio je ohun eye fun won lati tete fa ara won leti nipa iwa ko-bakungbe yi ju ki alaga sese ma to won s'ona eto Ile Igbimo lo,

ABO ORO TO FUN QMOLUWABI.

# LAGOS RACE CLUB
## GENERAL MEETING

A General Meeting will be held in the Island Club on Monday 12th September, 1955 at 6 p.m. Only members of the Club will be admitted and membership badges will be inspected at the door of the Committee room.

Agenda:— Minutes of the last Meeting.

Accounts.

Chairman's Address.

Appointment of Chairman.

Appointment of Committee.

Rule 11 " The Management of the Club shall be vested in a Committee of 18 in addition to the Chairman who shall be elected annually. Provided that no one shall be eligiblefor election at a General Meeting as a member of the Committee unless his name, duly proposed and seconded, has been handed to the Secretary at least 14 clear days before the General Meeting in question and the list of such nominations shall be available for inspection at the Secretary's Office 7 days before the meeting x x x x „

Rule 12 x x x x x " Any Full Member wishing to move any resolution at any Annual General Meeting shall give notice in writing to the Secretary at least three days before the meeting. "

# Ija Qsanyin Pelu Qrunmila

Lati Qwo ESQ IKOYI

Ki a to bere itan yi, o ye ki a se apejuwe ohun ti Ife je Ifa je ohun elo ti Orunmila ma nlo lati fi wadi ohun gbogbo, kakiri ile Yoruba, pelupelu o je okan ninu awon igba Mole. Awon ohun elo ti Qrunmila nlo lati fi wadi oro ni, Ikin, Opele Iporu, Agbigba, Erin ati Erindinlogun.

Qsanyin je okan pataki ninu awon Irunmole ohun elo re si lati ma soro gegebi ara Orun (Egungun) Awon ohun pataki ti o nlo fun iwadi oro tire ni wipe o nlo Afose, Aje, Oso, gbogbo won lo si ole ati ero.

O se ijoje kan ti Orunmila ati Osanyin pade ara won, ede koyede be sile, lobe ti Osanyin fi leri so ni iwaju Orunmila wipe kini yio fi on se, ati wipe ko le yan on mo ebo.

Orunmila gbo eyi, o dide lo sile, Nigbati o dele, o gbe ipuran re janle, o ri Qkaran Turupon, o si bere si ki bayi.

oyigi lawo oyigi Oyigi lawo oyigi Ati dide li a mo agba Ilesi Awon lo difa fun Qsanyin lojo ti o mba Qrunmila leri po Ko le yan on mo ebo, Qkanran Turupon.

Nigbati Qrunmila difa yi tan, o tun pada si awujo Irunmole nigbayi lo wa fe oro na ta pelu Qsanyin awon mejeji si saka si ara won, nwon si tuka.

Bi ile ojo keji ti mo, beni Qlofin ranse pe Qrunmila ki o wa ye Ifa wo fun on. Bi Qrunmila ti de, ti o gbe Ifa re janle, o tun ri Qkanran-Turupon, nigbana, o mo wipe oro Qsanyin lo nfe sele yi.

Orunmila kigbe hal, o wipe ki Olofin yan awon Qluso soju ona Afin nitoripe ao ru igi kan wo Afin wa loni.

Samo-samo, okan ninu awon iyawo Olofin ti ko ri ihoriho okunrin ri, titi o fi di arugbo, lo ro aropin igbesi aiye re lati lo pokunso. Bi o ti nfe se be, beni Osanyin ri, o sare si i, o si bere kili oro na ti je ki o to dibe Obinrin na si rohin fun u. Osanyin sunmo nwon si mo arawon O wa dide lati ma lo, ni obinrin na dimu wipe, on ko mo pe bayi ni nkan na dun to, ayafi bi o ba tele ou kalo sile, on yio fi pamo sinu yara on, Qsanyin si gba be.

Beni obinrin na ba di osanyin mo arin igi, o si nfe gbe wo Afin oba, ki awon oluso to gba eru igi na lori re, nwon si gbe lo siwaju Qlofin.

Qlofin tun ranse lo pe Orunmila wipe nwon ti gbe eru igi na de. Nigbati o de, Osanyin nrora ke si Orunmila wipe, mo d eru re loni, pa mi sile, ma se pa mi sode.

Qrunmila sa loju anu jojo, o wi fun Qlofin pe ifa lo gba eru igi na, ki o yan enikan lati ba on ru eru igi na lo sile on ati fi bo Ifa na.

Nigbati Orunmila de ile otu Osanyin sile, Qsanyin wa bere si fi ori bale fun Orunmila wipe, to, to, to, fun u; mo di eru re loni. Ayani, o ri i, Osanyin nfi ori bale fun Ifa titi di oni.

Akiyesi

Enikeni Ti O Ba Nfe Ra Iwe Irohin Eleti-Ofe Ni Ilu Tamale Ati Agbegbe Re, Kio Lo Si Qdo:-

QGBENI RAJI ALAGBE
House No H 75. Tabi Tamale
Central Market
P.O. Box 95,
TAMALE

## S lawu Lawani Joba Rikisi Pin

**Eko** Lose to koja, ni awon fi Qgbeni Salawu Lawani je oye Qba Itire ti awon ope ni Onitire. Eto ifijoye na bere ni dede agogo meji osan, Qgbeni F.A. Ola Akapo ti ise Olori Qmoba Itire l'o se eto ifijoye na loju ogunlogo awon enia pataki-pataki ati awon Oloye ilu Eko.

Ni asale ojo ifijoye ku ola, ni awon ebi, Qre ati ojulomo ta idiku ti a ko oye Onitire si mo'ri, ti awon fi jo kakiri ilu Itire ati awon agbegbe re.

Oloye Aromire ti ilu Eko l'o so itan bi o ti se je wipe Qgbeni Salawu Lawani ni o ni lati je oye Qba Itire.

Awon Saraki enia to peju pese sibi ifijoye na ni Alaiyeluwa Qba Eko, ati awon Ijoye re, Qlola Okunlola, Loya L.J. Dosunmu, Alufa E.M. Fisher pelu awon egbe Ile Isin ti St. Johns ati awon egbe Basiri, Qgbeni D. B.A. Johnson, Yaya Oluwa, J.B. Bankole J.K. Hototu, Olarinde, Ajose ati opolopo awon gbajumo enia ti a kole daruko tan.

## Idahun Si Ibere Bello

Olotu,

Gba mi laye lati dahun si ibere Ogbeni S. O. Bello ara Abidjan ti o mbere oro yi, Nje Muhamad ti o de gbehin lo da esin Imale sile?

Idahun: Beni, on lo da esin Imale sile. Anobi merin ni Olorun fi oro ran nise si awa enia. Anobi Musa ni Olorun fi Taoreta tabi Itan lailai ran nise. Yisa tabi Jesu ni Olorun fi Injila tabi iwe Itan titun ran nise, Anobi Dawuda tabi Dafidi ni Olorun fi Zabura tabi iwe Psalm ran nise, Anobi Muhamad ni Olorun fi Alukurani ran nise.

Ibere keji. Esin wo ni awon nwonyi se ki nwon to loruko meji meji?

Idahun. Idi re ti awon fi loruko meji meji loju tire ni wipe, larubawa ati omo Israel, omo baba kanna ni won, Abraham lo bi won. Yisa ati Jesu je okan, Musa ati Mose, okan. Job ati Ayuba, okan, Moriyamo ati Maria, okan, Sulaiman ati Solomon, okan, Joseph ati Yusufu je okan. Die die ni ede won fi yato si ara won gegebi ede Ijebu ti yato die si ede Oyo. Sugbon bi e ikini ba soro, enikeji ngbo lai wa ogbufo nitori Yoruba ni gbogbo won nse.

Lemomu Ajakuta.

## IMORAN FUN ENYIN ABIYAMO


**Enyin abiyamo e wa ra OMORELA o dara pupo fun awon omode.**

A ma je ki omode ri orun sun daradara o dara fun otutu iko ati orisirisi arun miran ti o ma mbi omode ja ni asiko ehin. Opolopo abiyamo lo ti lo egbogi yi fun omo won ti won si so wipe o dara pupo fun awon omode.

**OMORELA BABY MIXTURE**

*(SILE MEJI ABO 2/6d. FUN IGO KAN)*

O wa lodo :—

COMMERCIAL MEDICINE STORES

(Qualified Chemist)

10, VICTORIA STREET, LAGOS


## LQWQ IKU OJIJI OLUWA RERE GBAWA

Qgbeni A. UDOFIA ti ise akowe ile eru Ibi ngbeti (Custom) ni a gbo wipe, o yi subu lori aga ijo ko re mbi ise to si f be de oran.


## Egbogi Ti Colgate Ti A Fi Nfo Ehin Nikansoso Lo Daju Ti O Si Nmu Ireti Wa Fun Opo Enia

**LOSAN ATI ORU KO NJEKI EHIN ENIA BAJE**

Lilo ti opo enia nlo egbogi yi fihan wipe egbogi yi ko njeki ehin enia baje pelu egbogi Gardol. Awon Alase isegun ehin ti se ayewo re fun odun kan pe egbogi na ko nkuro beni ki nsa. Bi o ba sa ti nlo ni ojojumo, laro ati ni ale, ko ni jeki ehin baje t'osan t'oru.



Sodium N-Lauroyl Sarcosinate

SAME FAMILIAR PACKAGE



OKAN NINU AWON OJOGBON ONISEGUN EHIN TI SE AYEWO ORO YI.

A ti fi Ododo oro yi han nipa iwe ti awon Onisegun ehin te, awon si ti gba wipe egbogi ehin ti Colgate pelu Gardol je eyi ti o dara fun ehin to baje ju egbogi miran lo. Nitoripe egbogi Gardol ki njeki ehin baje, lo se jeki awon alase gba wipe egbogi Colgate ati Gardol lo dara julo.




Ko si egbogi ehin kan ti o dar bi eyi.
Ko ni jeki enu re run
Ko si ni jeki ehin re baje.

**O Dara T'osan T'oru Ko Njeki Ehin Enia Baje.**

## Anu Olorun Po Jojo

Bi o ba se wipe Olorun Oba dabi awa eda enia ni ko ba ti se ohunkohun fun wa. A gbo irohin lati ilu Ibadan wa wipe, okunrin kan, ara ilu Saro, ti o je wipe nigba gbogbo ti o ba bi omo ni omo na ma nje abiku. O si ti to igba mefa ti iru eyi ti nsele si okunrin ara Saro yi.

Samosamo, a se ko gbo ede Yoruba daradara, ni gbogbo bi awon aladugbo ti nwo wa ki i, ko gbo ohun ti nwon nwi.

Okunrin kan ti a npe ni Kasumu ti o ti nse iso Oluko ri ni ile Eko Forobe ni Saro, s gbon ti o wa ngbe Eko nisisiyi, gbo nipa ohun ti o sele si ara ilu re yi, o lo lati ba kedun, o si ndeko fun wipe Olorun ti o fi omo fun l'o gba a lo.

Saro na tagiri o wipe tani eniti o nje be? o wi fun wipe Olorun l'o nje be, beni Saro na dide, o jade si ode gbangba, o di ese o na a soke orun, o wipe ki Olorun bo sile ki nwon jijo ja. Sugbon bi Olorun ti je alanu to lati igba na wa, okunrin Saro na ko tun bi abiku mo. E o ti wipe Alanu ni Olorun. Iba se wipe Olorun da esinsin ki o tobi bi esin, atapa ni iba tani atapa ni iba ta enia.

---

## Idajo Adelabu Kusi Dede

**Ibadan** Nigbati nwon pade ejo ti awon olopa mba Ogbeni Adegoke Adelabu ro wipe o tabuku si Kotu ati pe o se afojudi si adajo Kotu Oja'ba keji, on pelu Ogbeni L. Ade. Bello ti awon fi sun esun wipe o gba adajo l'eti.

Agbejoro Oba Ogbeni Adedipe so fun adajo ninu oro re wipe Adelabu to si Kotu lati lo fi ajulo han adajo ni. Nitorina, o ni ki adajo wo oro na, yio ri wipe awon mejeji, Adelabu ati Bello jebi esun ti a fi won sun na.

Adajo fi idajo re si ojo kedogbon osu yi.

---


## SOUVENIR OF OUR LIFETIME!!!

Commemorative Brochure

ON

UNIVERSAL PRIMARY EDUCATION

IN THE

WESTERN REGION OF NIGERIA.

Coming Shortly

18 coloured pages of interesting photographs and a review of the Free Primary Education Scheme. It opens with inspiring messages from the Governor and the Premier of the Western Region with their photographs.

There's a message too from the Western Regional Minister of Education and a calendar of important dates connected with the introduction of the scheme early this year.

You Can't Afford To Miss It. It's a Treasure of a Lifetime produced by the Ministry of Education, Western Region, Ibadan, and designed and printed in London.

Order your Copy NOW. Price-Six Pence.

From your local newspaper Agent or the Western Region Information Service.


## Afiko S'ebi F'ara-korin

EKO— Odomobinrin adelebo kan ti oruko re nje Esther Ogunko ni o fi oko re ti o nse ise olopa oba se arakunrin re lori owo ti baba re fi sile fun Esther ati arakunrin re Micheal gegebi ogun (Will) pe ki nwon o pin ni ogbogba larin awon mejeji.

Nigbati baba awon omo mejeji na ku, ofi ponwa merinlelogbon ati kobo merin (£34, 0. 4d) sile gegebi ogun re (Will) to se, o si fi si abe itoju Alabojuto ohun isura ti Ijoba (Administrator General.)

Lehin isinku, Esther mu oko re Ajayi Goldien ti ise olopa oba (Policeman) lo si iwaju Alabojuto pe arakunrin on ni, nwon si gba owo na nwon na gbogbo owo na patapata

Ki a ma fa oro gun mo, nigbati oro na de iwaju Adajo Kotu, Esther ko fi oro re bo epo bo iyo, o ni on jebi sugbon gbese ti on je n'pa ti isinku baba awon ni on fi owo na san

Adajo so wipe anu Ajayi se on nitoripe iyawo re l'ofa si ijogbon na ati pe iwa ti eti ro girigid ki eto mu se ni ise ti e se, nitorina, ki enikokan l'oko-t'aya lo san ponun medogun-medogun (£15) tabi ewon osu meji-meji.

Enyin okawe wi, e fi eyi k'ogbon o!

---

## Alfa Kelani Di Olori Oniwasi

OKE - OGBE Awon Musulumi Oke - Ogbe ni agbegbe Ebute - Metta ti Alufa Kelani je olori awon alufa Oniwasi, o si bere si se wasi oro Olorun ninu egbe Taoyidi - Deen, Oke - Ogbe ni ojo keji osu July, 1955.

A tun gbo wipe awon egbe Samusi - Deen ti abule Akinwunmi tun fi alufa Kelani je Oye Seriki Musulumi, lehin eyi ni gbogbo awon aroko parapo sinu Mosalasi Jimo ni Iwaya tun fi Alufa Kelani Oke - Ogbe je olori gbogbo awon Alufa Oniwasi ni Aroko.

Ni ojo kerin osu May, 1955 ni awon egbe Omo Ajase ni Agege - Odo tun fi Alufa Kelani Oke - Ogbe je Oye alufa egbe won. Ohunkohun ti awon egbe na ba fe se alufa Kelani Oke - Ogbe ni yio ma ba won se.

Oye a mo'ri o.

---

## Osika, Ba'le Ku, Eniba Da'le A Bale Lo

Nilu kan l'ona Ojo ni agbegbe ile Awori, ni okunrin kan wa, ara Sabe ni, oruko re a ma je Sarumi Olopo eru, o buru o si ni ika ninu ju Ibaka lo.

Okunrin na ni orisirisi ogun buburu lowo to fi nse enia nika, okan pataki ninu awon ogun re ni ogun ojo fifa, bi o ba si fila ori re ni gbangba ita, kia ni oju Sanmo tabi oju orun yio yi pada ti ojo nla yio bere si ro.

Eyi ni ogun to saba ma nlo ju nitoripe enikeni to ba fe se nkan ni n, bi igbeyawo tabi isinku, bi oluware ko ba fun ni owo pelu oti, ojo ko ni jeki nwon gbadun.

O tun ku okan, bi okunrin na ba jan fila re mole, to ba daruko enikan si, aradun l'o ma san pa oluwa re, o ti fi ogun buruku yi se opolopo jamba fun awon gbajumo ilu to ti pa won danu.

Ni ojo kan, okunrin kan ro inu arare titi wipe ona wo ni on le gba fi pa basira enia buruku yi re ? o wa ranti-wipe igi Araba kan wa ninu igbo ilu won ti alijonu re gbona girigiri, bi enia ba puro mo igi na, egele gbe oluware.

Okunrin yi wa pe awon ara ilu jo, o so fun won pe igi Araba n'a so wipe enikeni ko gbodo sunmo Sarumi, Olopo-eru-mo o, nigbati Sarumi gbo bayi, o binu pupo, o ni on yio lo pa igi Araba na O lo sinu igbo bi o ti duro sidi igi Araba yi ti o mu fila jamba re dani lati jan male' ti o nso wipe igi Araba yi ni ki aradun san pa, koi to jan fila mole igi Araba ti l'anu logan, o si gbe mi. Nibe ni Sarumi ika enia pare si.

Bayi ni aseni fi se arare o

**REDIFFUSION**

THE BOX THAT TALKS SINGS & BRINGS MUSIC TO YOUR HOME

Costs less than 3d a day and gives you pleasure for 17 hours.

MAINTAINANCE FREE! ARE YOU A SUBSCRIBER?

## G-bin-gehin

Dan egbogi yi wo fun 'n ti o ba di wipe ehin ndu enia de ipo ti ko le bere. Kindrin lo fa a Nitoripe ise Kindinrin ni lati se idoti kuro ninu eje ara enia. nigbamiran ewe ko ni sise deedee. Ehin ti o dun ni je ikilo fun enia wipe Kidirin re ko s'ise to, o si nfe iranlowo egbogi De Witts ni a lero pe o le je iwosan na Nitoripe egbogi na ko se iru ise be ti ri. Dan wo, lo ra okan wo ni sobu.



Ohun to da wa loju ni wipe Egbogi DE WITT,S je eyi ti a se toto'toni ohun elo re gbogbo lo si mo.

DE WITT'S PILLS
for Kidney and Bladder Troubles

## Owo Te Omo To Pa Baba Re

**Ogut** Gambir na Fulani ko lejo ninu, eran oba l'ofisu oba je, ko le d'ogun sugbon eyi ko ti be l'abe Asia Gesi. Nitu yi owo te odomokunrin to pa Baba re.

Gegebi irohin ti de odo wa, a gbo wipe omokunrin yi sun ti Baba re ninu yara kanna, nigbati omo ri wipe orun ti gbe Baba re lo, lo ba yo apola-igi lo gbe le Baba re latari, ni Baba ba fi igbe ta.

Bi Baba ti nwa ona lati bo sode beni omo yi fi obe si i ninu, o si ge inu Baba re werewere, awon olopa ti de ibe, nwon gbe Baba lo si ile iwosan, nwon ra omo na mu.

Ejo wa lodo awon olopa nisisiyi, sugbon Baba ti ku.

## Pulowo Oja Re Sinu Iwe Iroyin Eleti - Ofe

No. 73/S.2/Vol.IV/865.

# Ministry Of Education. Westen Region.

## TEACHER TRAINING COURSES FOR MODERN SCHOOLS.

Courses for training teachers for secondary modern schools will begin in January 1956 at the Government Teacher Training College at Ibadan, Abraka, (men), and Ilesha (women). These courses will be of two years' duration.

The salary scale attracted by a successful completion of the course will be determined after consultation with the Terms of Service Committee, but in any case will not be less than that paid to holders of the Teachers' Grade Two Certificate.

Applications will be considered only from the following categories:

(i) holders of the Cambridge Oversea School Certifi-
(ii) cate, holders of the General Certificate of Education at Ordinary Level,
(iii) holders of the Royal Society of Arts Senior School Commercial Certificate in English and not less than four other subjects as prescribed in the Regulations of the Royal Society of Arts.

Applicants must be sponsored by a local authority, or a voluntary agency (including the proprietor of a private institution).

Any person who gains admission to one of these courses, and who is already a certificated teacher, will receive his present salary less £20 per annum deducted at source in part payment of subsistence. Employers will be eligible for grant in respect of these payments.

Other persons who gain admission will receive an allowance the rate of which is at present under review, but which in any case will not be less than £36 per annum.

Applications should be made direct to the Principals of the Government Training Colleges, through the sponsoring agency.

Applicants who wish to attend similar courses which will commence at the same time in various Valuntary Agency Colleges should apply to the appropriate principal in the usual manner.



## SPORTS TO-DAY

### NIGERIAN CHALLENGE CUP

By Bashiru Odukotun

E.C.N. v S.C.O.A. To-night at 5 p.m. all roads will lead to the King George V Stadium where E.C.N and S.C.O.A. will engage themselves in a grim battle. It will be remembered that S.C.O.A. played in the Finals for Lagos Zone last year, and was beaten by Kano.

Barely seven days ago, the E.C.N held the Railway Boys to a 2-3 game in the League Competition. It is with this spirit that the Electricity Boys will hold their opponents at play when they meet to-night. Fans have expressed confidence in the S.C.O.A. particularly when they are meeting a team like E.C.N. But things dont always go as we expect it.

As for Tarberer, E.C.N. left full back and the only European in the team, it will not be easy for Cyril and Dike in the S.C.O.A. forwards to-day.

UAC beat MARINE. Last Saturday at the King George V Stadium marine disappointed thier supporters and went tumbling before UAC 2-4. The defeat of marine actually lies in their forward line. Anieke, Sambo and Salvador all combined effectively to win the match for the UAC.

Next Saturday, same time, same stadium, the Railboys will try it out with the UAC for the second semifinal of the Competition.


## OBENTE DI OPELENGE




Iwenton-won ti ni gbogbo nkan nfe. Bi enia ba sanra Pasanju, wahala ni. Orisirisi oruko-ebu ni a fi npe iru enia dungbe he. Die ninu won ni Obente, Qrombo, Ikomade, Onikunla, Qra ati Qbe. Ijogbon ni fun won lati rin, lati Sare, lati gunke ati lati sise. Gbogbo nkan ki pe su won. Bi nwon ba si ti tobi to ni aisan won nyo won lenu to. Oni ori, ola orun ki ntan lodo won. Mu itiju ati itiya kuro lara re nipa lilo „THYGLOIDS" Tablets to nso Obente di Qpelenge. 7/6d. Pere ni. A tun ni „THYGLOIDS" Ointment ti o nso ese Banti di tere. 4/6d. pere ni. Owo-oko je 1/6d. Wa ra won lodo wa.

**The Egba Trading Aradan Stores,**

18, Denton Bridge Street,
P.O. Box 2,
Ebute Metta



# AWO IKORIN (RECORD) TI DECCA



yio mu awon orin ti o fe ati awon akorin wa sinu ile re

## Lo ra won ni sobu

## S. C. O. A

A ti da Eka titun kan sile ti yio [illegible] ma fi awon ero [illegible].

## S. C. O. A.

Head Office :- 40 Marina Lagos

Show Room Martins/Broad Street Lagos

ATI NI

Ibadan, Sapele, Warri, Onitsha, Calabar, Aba, Port Harcourt, Kano, Enugu, Zaria & Sokoto.


Printed & Published by The Union printing and Publishing Company, 28 Kosoko Street P. O. Box 467 Lagos Phone 23370